## Owe

Owe ni ẹṣin ọrọ lojo ti ọrọ ba sọnu owe ni a fi nwa. Nigbati esinṣin njẹ Kudayisi, ẹnikan ko gbọ ẹnikan ko mọ, ṣugbọn nigbati Kudayisi wa jẹ eṣinṣin ni gbogbo aiye wa gbọ, ti aiye mọ.


# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.



## For Sale

One Ford Saloon Car In good Condition Owner bought new one:-

Price £300 or nearest

*Contact:-*

Y. S. AGUNBIADE
4, Agunbiade Street
MUSHIN


VOL. V No. 209 MONDAY SEPTEMBER 4 — SEPTEMBER 10 1961 KỌBỌ MEJI (2d)

# Awon Omo Baba kanna so ara won di egbon Joseph nwon gbe aburo won ta ni Odunrun Poun

EKO:- A GBỌ IROHIN WIPE ABUDU LASISI ATI ABURO RE TI NWỌN JIJỌ JẸ ỌMỌ IYA TI NWỌN NGBE NI ABULE BARIGA NI NO. 10, OGUNDELE STREET, NI NWỌN SO PANPA PAPỌ TI NWỌN SI KI ABURO WON TI O JẸ ỌMỌ BABA WỌN MỌLẸ, TI NWỌN SI LỌ GBE TA NI ERU FUN ỌDUNRUN PỌNUN. ORUKỌ ABURO WỌN NA NI SALAWU AJAO.

Ọkunrin kan ti o njẹ J. Agbooọla ti iṣe ọkan ninu awọn Ọlọpa Inu sọ fun Adajọ ni Ikẹja pe, nṣe ni awọn enia na fẹ lati ma ṣe owo ẹru kakiri

Agbooọla sọ fun adajọ wipe ọkunrin kan ti o njẹ John Omose ti o ngbe ilu Ṣomolu lo wa sọ fun on wipe awọn ọkunrin meji kan mu aburo wọn wa si ọdọ on lati ta ni ẹru, o ni nwọn bẹ on pe, ki on ba awọn wa ẹni ti yio ra ọmọ na ni Ọdunrun Pọnun (£300).

Nigbati o ṣe ni awọn ajọmọgbe mejeji na fi ẹsẹ wọn rin wa sọdọ mi, nwọn ni ki nba awọn wa ẹniti yio ra ọmọ na.

Ọlọpa na sọ fun wọn pe, iyẹn ko ṣoro bi nwọn ba le ṣe iwe adehun fun on, lọla ni on yio fun wọn ni owo. Ko pẹ lẹhin na ni ara fu wọn, ti nwọn sọ pe awọn ko le ta aburo wọn na ni £300. mo ati pe nwọn ti ri ẹniti yio ra a ni irinwo Ponun Nigbati nwọn nka owo lọwọ ni awọn Ọlọpa ba ki wọn mọlẹ. Ejọ na si wa ni kọtu bi nwọn ba si ti ṣe e si ẹ o ma gbọ.

## Sa wo bi awon alagbara ti nsubu, Isaac Thomas lo, ko'dagbere



Orukọ Isaac Thomas bẹrẹ si han nigbati nṣe iṣẹ labẹ Iwe Irohin Eko Akede Eko ni iwọn ọdun 1920 gẹgẹbi Olotu kekere (sub Editor) Prof. Adeoye Deniga ni Olotu agba nigbana.

Nigbati o di ọdun 1928 lo da iwe Irohin Akede silẹ, Iwe yi ni nwọn ma npolowo rẹ bayi ni ọdun 1930 pe, Akede Eko li ede Yoruba gbangba dẹkun kedere bẹwọ, ọrọ ikọkọ tan nibẹ. Iwe rẹ yi ati Eko Akete ati Eleti Ọfẹ lo jijọ nṣe ilu ni akoko ti ọtẹ le koko bi oju ẹja. Ekunrerẹ itan Akede Eko yio jade nigba miran.

E wo awọn ti wọn duro ninu aworan oke yi, ko si ọrọ ẹrin lẹnu ẹnikan ninu wọn. Ẹniti o wa ni iwaju awọn ero ti o duro ni Ọgbẹni Bọlaji ọmọ bibi inu Isaac Thomas Ologbe yi, ẹ o ri nigbati o mbu erupẹ si boji Baba rẹ. Ki Ọlọrun jẹki ọmọ gbẹ hin wa Amin.

## Ina eedu pa Tokotaya sinu ile ni Jos

A gbọ irohin wipe awọn enia mejitokọta ya ku nigbakanna sinu yara kanna.

Bi a ti gbo ọrọ na lọ niyi, Ni alẹ ọjọ kan ti orinrin otutu mulẹ kiji kiji ni Ilu Jos, ni Malam Musa Gongo ati iyawo rẹ ba dana eedu sinu adiro, nwọn si gbe ka inu ile wọn lati jẹki inu yara won ma lọwọrọ.

Bẹni tọkọtaya wọn gbagbe sun lọ, lai dena pẹnu, oru ina ra lo sin awọn mejeji de ọrun alakeji aremabọ. Ọrọ na si mbẹ ni ika wọ awọn Ọlọpa.

## Ijoba Alapapo fe se Ajodun Ominira ni ilu Eko

EKO:- Ọgbẹni N. Nwangbo ti iṣe aṣoju fun Ilu Is'ẹlu ninu ile Igbimọ nla (Reps) o bere lọdọ Alhaji Tafa wipe, nisisiyi ti oṣu October ti mbọ wa, ti a si gbọ wipe Ijoba Alapapọ fẹ ṣe ajọdun odun kan ti a gba Ominira nilẹ Naijiria, Bawo ni a o ti ṣe awuye-wuye na, ati kini yio ti pariwo to?.

Ọlọla Alhaji Tafa dahun wipe, a ni lati ṣe ayẹyẹ fun Ominira ilẹ wa ti o pe ọdun kan ninu oṣu October 1961 yi, ṣugbọn a ko ni ṣe e ni alariwo rara. Ko nṣe ohun ti a o pe awọn Ilu ekere wa ba wa yọ gẹgẹbi iru eyiti a ṣe lọdun to kọja, Olukuluku yio ṣe ajọdun tirẹ ni Ilu rẹ, gẹgẹ bi agbara wọn ti mọ.

# SE BOTIMO

## Apa Kinni (1)

Lati Owo:— Funmilayo Kofoworola.

Gegebi mo ti so loso keta sehin pe, ngo bere si fi Itan mi oloyinmomo yi da enyin Onkawe Irohin Imole lara ya losoie. Eyi ni o jeki mbere apa kinni Itan mi na, ti Oluwa ko ba ko fun eru re, e o ka Itan na fun odun kan gbako.

Itan mi na lo bayi pe: Nigba lailai awon okunrin Olokiki meji wa nilu kan, oruko ekinni a ma je Nini-owo-ko-gboju-boro, e k e j i a si ma je Sebotimo, awon mejeji yi je ore kori kosun, aso kan soso na ni won jijo ma nda, ki nto ma ba I t a n na lo, o ye ki nse alaye nipa olukuluku won.

### IRU ENIA TI SEBOTIMO JE

Sebotimo je Oniwapele enia, ko gun beni ko si kuru, awoja enia ni ise, o dara bi omoge, iwo enia re dabi enipe o neju bi obinrin eyi jeki won so m oruko arinje won a si ma pe ni Eleyinju Ege, ju gbogbo re lo, ki dawole nkan ti agbara re ko ka.

### IRU E N I A TI NINI-OWO-KO-GBOJU-BORO JE.

Niniowokogbojuboro je enia ti o sigbonle foinsa, ko bikita fun enikeni, ko si ko lati ba enikeni ja, ohun ti ko to ni o ma dawole, ki wo aso ni iwonba ti mekunnu, a fi mura bi O b a, ko si ko l a t i fi emi re wa owo. Enyin ko ha ri pe oruko awon mejeji nro won? Iwa ti Olukuluku won ni yi ko ba ore won je, nitoripe won mo owo ara won.

### AKO APON NI AWON MEJEJI.

Ni ojo kan Niniowo da nimoran fun Sebotimo pe, o to asiko fun awon lati gbeyawo, nitoripe agba ni awon nda yi. Sebotimo si da lohun pe, loto ni o to ti o si ye ki awon gbeyawo, o h u n ti a fi nse Oko Iyawo nko? Niniowo bere lowo re pe, ohun ti a fi nse oko Iyawo bi bawo? Sebotimo ni Owo ni, nitoripe laisi Owo, eko yepere ni Oluwa re yio je.

Niniowo si fun lesi b a y i pe: Bi o ba je ti emi ni o ngo wa owo ni tipatipa, ngo si ri, nitoripe ko se fi oju boro wa, bi o kan ti oso ngo se, bi o kan ti k i n l o be awon Irumale inu igbo ati ti odo wo ni, ki nfi le ri owo, ngo se be o. Mo daju pe ti mo ba wa s hin wa sohun, ti mo ba wa ni I w a k u w a yio yo si mi lowo. Emi ti mo wipe Esu ni o nro owo l'agbede, ti mo ba mu lere, yio bu owo fun mi tabua.

Sebotimo paapa fesi si oro re o ni: Ha ore mi, jeki a fi ohun gbogbo le Oluwa lowo, ki a ma si dake adura, gbogbo re ni yio se fun wa. Owo Olorun lo dara ju, Omo omo yio ba ohun ko hun ti enia ba fi owo Olorun na se ko ni ba je lailai. Jowo nitori Olorun ma thori Igbona ra owo so pe esu ni Iwo yio ba sore, nitoripe esu ko ni ise meji, a fi Ibi.

Eniti o ba si se tire, lna ajoku ni yio gbehin si ni kehin aiye re. Nitorina Oluwa yio fe Iyawo rere fun wa Akiyesi lose tombo lagbara Olorun e o nia ka bi awon mejeji ti fe Wundia kookan sona ati bi nwon ti se dajo Idana sona ti Olukuluku si wa owo lo, ati bi Babalawo ti se la won loye ibiti won yio wa owo gba. O di gba kan na.

## Olotu ile ise U. A. C. nlo si Ilu Oyinbo fun Faaji

IFE:- Agbo irohin wipe Ogbeni W O. O l o t u ti nse alabojuto ile ise Oyinbo Onisowo U. A. C. ni Ile Ife gba Isinmi olofe lo si Ilu Oyinbo, labe itoju U. A. C. LTD.

Nigbati o ba de ilu Oyinbo yio lo si Sobu Ibiti nwon ti nta awon oja bi ohun jije (Provisions) ati ibiti nwon ti ngba epo, Ekuro, KoKo, awo, ati gbogbo nkan bawonni.

Yio lo si ibiti nwon gbe nse Awo, Pano, Abomafo, ati Aluminium, yio lo si sobu ibiti awon gbe nta Egbogi ati nibiti nwon nta Lofinda, ati awon nkan ti Obirin fi nse Pepefuru fi tun ewa won se.

Yio se idanwo bi a ti nse ise Olotu ati bi a ti nse alabojuto ise ki o to pada wa le.


AWON IWE KO SE MA ...
IWE EGBOGI FUN
ONIRURU IWOSAN.
IWE ADURA ISEGUN AWON AJE:
IWE IFA AGBON-NIREGUN, IWE
ITUMO ALA PELU IWADI NKAN:
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU:
★★★ ★★★
IWE ADURA TETE DA MI LOHUN:-
IWE ITAN ABALAIYE ATI TI ISEDALE



KOWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA

MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture je Ogun Iko pataki ti a se ni asepe lati wo awon Iko origirisi san ni kiakia. O dara fun Iko agbalagba ati Iko omode beni o si tun dara fun Iko omo owo pelu.

O dara pupo ju gbogbo ogun Iko yoku lo. O dara fun awon arun Iko wonyi, Iko ti o ma nba enia ni ohun, Iko ti o ma npon enia leju, Iko ti ki je ki enia sun dada, Iko ti o ma ndun enia legbe, I k o ti o ma nta enia ni aya, Iko ti o ma nfa Efori, Iko ti o ma nfa are ba ara, Iko ti o nmu ki enia ma po eje, ati awon Aisan m i r a n ti won somo Iko bi aiperi, oyi ete.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupo fun enyin ti Iko nyo lenu, E ma se sahun fun alafia ara yin, alafia ni opin oro ijafara ni ewu pupo, tete lo ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo re, Igo kan re je 2/6d' arapo re je 24/-.)




LILO RE:-

Omo osu meta—Idaji sibi tea kan ni wakati metameta
Omo osu meta si mejila:- Sibi tii kan nigba meta lojojumo
Omo odun kan si mefa:- Sibi tii meji nigba meta lojumo
Agbalagba............Sibi Imuko kan nigba meta lojumo

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos, Nigeria. Phone 22515.

34, Docemo Street, Lagos. Phone 24247.

# Petepete T'ana ni popa

Lati Qwq:- DELE ATOLAGBE

E MU IWA IKORIRA YI KURO.

Ni owuro yi, mo fẹ ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imolẹ fi ọgbọn ati lakaye gbọ ọrọ mi yi dada. Ni ilẹ Naijiria ti o jọ ti Hausa, Yoruba ati Ibo iwa kan ṣoṣo ti o buru patapata ti a si fẹ mu kuro lọkan ara wa ni iwa ikorira ẹnikeji ẹni ti o si le rọ orilẹ ede silẹ kiakia.

Enyin enia wa ni ẹku mẹsan Oro ni mo fẹ ba sọrọ gidigidi, nko si fẹ ki o binu ju iwe yi si ibikan jọwọ ka a ki o si gbọ ọrọ otitọ ti o wa ninu rẹ. Ko si ọmọ imale kan ti Ijọ onigbagbọ fẹ ni ilu Oro. Bi o ti lẹ jẹ pe ọmọ binrin onigbagbọ fẹ lati fẹ ọmọ onimale kan, awọn obi ọmọbinrin na ki gba fun won. Kini o le fa iru iwa buburu yi? Bi a ba wo kakiri larin ilu Oro, a o ri wipe ọgunlọgọ awọn enia ilu Oro ni wọn jọ Kristẹni, ti ẹsin Kristẹni ko si le jẹki wọn fẹ ju iyawo kokan lọ! Ṣugbọn mo bi yin, ẹnyin ara Oro, Kini ẹ ti fẹ ṣe Ogunlọgọ awọn ọmọbinrin yin ti wọn koti lọ si ile ọkọ? Nitoripe ẹnyin obi wọn ko gba wọn laye lati fẹ ẹniti o wu wọn. Ṣugbọn bi ko ba si ẹniti o le sọ otitọ ọrọ na fun yin, mo ro wipe o to akoko nisisiyi ti o yẹ ki ẹ tu awọn ọmọbinrin yin silẹ ninu igbekun ti ẹ fi wọn si nipa aiko fun wọn laye lati yan ọkọ to ba wu wọn. Bi a ba woye dada a o ri wipe Obinrin lo pọ ju ọkunrin lọ ni ilu Oro, ni gbati ẹnikankan ninu yin ba ti ni iyawo tirẹ, bawo ni ẹti fẹ ṣe awọn toku nilẹ, a bi ẹ fẹ fi ọmọ yin ṣe Iyawo funra yin ni? E ṣe alaye fun gbogbo ara aiye lati gbọ.

Bi ẹ ko ba jẹki awọn ọmọ yin ni ọkọ to wu wọn ti wọn ba ṣe bẹ ya aṣewo si arin ilu Eko, ẹ mọ pe ẹnyin ni oju yio ti. Ki Oluwa ma ṣe doju ti gbogbo wa.

A ri pe ẹnyin Obi wọn nna owo lori awọn yin lọpọlọpọ, ṣugbọn o yẹ ki ẹ fun wọn laye lati fẹ ọkọ to ba wu wọn. Mo fẹ ran ẹnyin ara Oro ati Ilu miran ti o ba tun nhu iru iwa Ikorira bayi leti pe, ofin ilẹ wa ko gba enia laye lati fi ọmọ rẹ fun ọkọ funra rẹ a fi eyiti o ba wu ọmọ funra rẹ.

O to akoko nisisinyi ti awọn ara Oke-ọla ati Oro yio ma fẹ ọmọ lọwọ ara wọn yala o jẹ Onimale tabi Kristẹni Bi ko ba si irẹpọ larin yin, kiniṣe ti ẹ fi nṣe gbogbo nkan papọ? E jọwọ, ẹnyin ti ẹ jẹ Alagba ẹ bani ri si ọrọ yi Ẹniti o hu iwa ibajẹ nlọ si Oke ẹla bi ẹniti nlọ si Ṣokoto. Mo ro wipe ọrọ Oṣelu lo fa gbogbo edekoyede to wa larin wa yin, ṣugbọn o to akoko ti a o yọ Oṣelu si ẹgbẹ kan ki a rojn gbọ ti ara wa.

# Iku pa Akinsola Obashoyin

Lati ọwọ: FATAYI A. OYEROGBA (Bonny Gasper)

Iku iba gba owo, ṣe afnn lẹgbeje. Iba gba Aguntan ṣe a fun lẹgbẹsan, Nitori Akinṣola ju ẹgbẹrun aimoye owo silẹ lọ, Aki ku oruko rẹ wa lailai. Ẹkọ wo ni a o da fun ẹniti ẹku payarẹ, Ha! Ọga ile ẹkọ Prince College d'ẹni ọrun, Iku ki to wa gẹgẹbi ati wa saiye, nigba miran a fi agba silẹ mu ọmọde lọ, Osan gangan lo run rẹ wọ yi, Akinṣola Ibiti enia ko si Edumare mbẹ ni bẹ Akin gbogbo ohun ti o pamọ odi peregede fun ọ.

Irin a jo to gun ju bo pẹ titi a de opin, odo ti ogun ju bo pẹ titi a wo kun, Aiye ba dun ju oyin bo pẹ titi Iku lopin ẹda, Iku ayọkẹlẹ wọle alaṣọ. Afo gija sile Alakisa Iku ko ba ẹnikan ṣorẹ ẹni Jagun ri ni jagun npa. Ṣugbọn Iku ba gbowo Ebun, Julius Ọdẹyẹmi iba fun lowo, Iku ba gbẹbọ, ọmọ ile ẹ k ọ "Prince College" ko ba rubọ Ọkunrin magaji, Iku a dun ki bi ko ba sile, boba wọle kẹkẹ a pa mọ ni lẹnun on lo mu Akin lọ, Edumarere a dẹ lẹ fun Akinṣola, oku o tuu ku nilẹ o tan o tun gbinlẹ bi ọgẹdẹ, o di ru digba koto lọ laye dandan ṣe ẹni ọmọ sin ko tan laiye, Edumare ṣa tọju ọmọ to fi si'e. Ọba oke jẹkl ọmọ ṣe tọju wa. Babalawo kan ko ri ara rẹ loju ọpọn bẹni awo Irawọ ki ri ararẹ loju awo ojo to ba win olojo ni munilo. Iwo ika aseni banidaro iwọ ika apani mayọda oba ran Ojọ ati sun aiye kobadun fun Iwọ osika, ko lagbara lori Iku oniṣegun kosi ẹbọ Iku se bo titi Jagun afa ẹnilọ Iku komọ Itiju Iku ibamọ Itiju Kibapani.

Iku afi Ika silẹ mu ẹni sunwọn Agbeni lulẹ maleji ni dide sugbọn Igbẹhin lo'an oni ko jawẹjẹ ki otoku ẹni ọwọ roti sun ti ko le dide ẹni ko ku si titi kama wa apa kiri ati ori ẹto ri ki adupẹ fun Iku rere Edumare majẹ ki aku Iku Moto Yarabi maji ki aku Iku Omi, Waya

Mojuba Agba O! Aiye toto fun u.

**For all your Printing**

**Reguirements**

Invitations, Programmes, Hand Bills,
Pamphlets, Advertising
Material and all
Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

**Where Quality Print, costs less.**

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE
TI NWỌN PE NI:-

RICHALFT FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn RọbiRọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o burukun ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti wọn pota ni ilẹ yi

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ojulowo egbogi atata ti a nranṣẹ fun tita lati awọn ilu J a m a n i Faranse ati ti awọn Tatabulu Itali jẹ. Mọdaju wipe bi Ẹjẹ Ara ko ba mọ daradara awọn amọdi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ Laku r e g b e origiṣi Inarun, Ojuṣiṣu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Ayadidun Itanpara, ekuru lara.

Ara riro, LapaLapa Egbo ẹ s ẹ, Amodi Apo ileitọ ẹhin didun tabi Ibadi riro pẹlu egbogi Riṣaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ ma rẹ mọ tonitoni pẹlu Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## Iranse si Oludasile ati gbogbo Omo Egbe Imole Aiye

Lati Owo:- WULEMOTU AMOPE (Eko)

O fun mi ni Idunu pupo lati fi iwe mi yi ki Oludasile egbe Imole A i y e pelu gbogbo awon egbe na e ku orire, e ku ayo fun akoko egbe ti a o da sile labe iwe Irohin le de awon Baba nla wa.

Emi ki nse omo egbe, sugbon omo mi je okan ninu omo egbe na. O si dun mo mi nigbati mo nipa egbe na, ohun ni o mu mi fiwe yi ki gbogbo omo egbe na. Emi gigun ati Alafia ara ko wa pelu wa. Akoae Agba Olorun ko fi mo kuo mo lo, mo ki Olotu na asiri re yio ma bo Iwaju le o ma lo. Oduduwa yio gbe o.

KABO O! "EGBE IMOLE AIYE" KABO O!

Mo fi iwe kekere yi ki egbe na ku abo, mo ki oludasile egbe na pelu gbogbo omo egbe. Emi gigun pelu alafia ara Olorun ko fi to gbogbo omo egbe na. Amin.

Mo be enyin omo egbe, e jeki a mura lati ba awon elegbe wa to je omo jaiye-jaiye soro isiti ki nwon le ronu piwada, anfani nlanla ni egbe yi fun wa lati ma so nkan to ba ru wa loju fun araiye gbo o. e ku orire o.

Emi ni
OLANDO BABS OFFA

IMOLE DE, OKUNKUN PARADA

Ohun rere ni a o ma ri ninu "Irohin Imole" O tun gbe Omiran, oloyinmomo egbe Imole ni oruko egbe titun to sese tun wa saiye nisiyi. Anfani lo de fun gbogbo enyin odo ati agbagba, ohun ti oba ru yin loju ke kowe bere lowo Akowe Agba yio si fun yin lopolopo amoran nipa ibere yin. E le se bere lori awon omo yin to nlo si ile eko ati awon ibere daradara miran be lowo awon Omo Egbe Imole Aiye.

Pelu ifowosowopo enyin onkawe Irohin Imole mo ni ero wipe egbe na yio yori si rere.

Emi ni:- DELE ATOLAGBE

## Oba Gesi lo se abewo ile eko giga



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Alaiyeluwa Oba Gesi Elizabeth keji ni akoko ti o lo se abewo ile eko giga kan ti a npe ni Grammar School nilu Oyinbo, okunrin to wo ewu funfun ti o duro ti oba na ni okan ninu awon oluko nipa ogbon lo nfi ise ti nwon nse han Oba na. Akoko na si je igbati ile eko na nse ajodun irinwo odun ti nwon ti da ile eko na sile.

## OlOFOFO

Lati Owo:— "OMO ADE"

MO Ki yin, gbogbo enyin Onkawe Irohin Imole e ku Lailai e si ku a i r i n i aibere emi, mo si tun ki yin e ku ile tutu yi. e jowo e mase jeki nkan gbigbono jinna si yin rara paapa enyinarugbo wa.

Emi Olofofo tun de sugbon mo fe ki e mo daju pe emi Olofofo ko ku boni ailera ko gbe mi de, sugbon mo ti dake fun odindi osu meta sehin mo nwo Ibaje awon Oselu wa pelu Ibaje araiye.

ENYIN OSELU MUSHIN KINI E NWO?

Enyin Oselu Mushin emi ko ni fe ki e binu si, emi Olofofo rara bikose pe ki e jeki a jo fi owo sowopo jo sise ti Olorun ran wa.

Ohun pataki ti mo ri nipe gbogbo Ile Eko Mushin ni o je Alapa ti o je Ewu n l a n l a fun gbogbo awon Oluko ati awon omo Akeko. Oro ti emi Olofofo ba yin so yi ki se oro ti a le ka ti a si le fi rerin lasan, bi ko se pe ki e ka ki e si mu eyiti e o se ni kiakia.

Gbogbo Ile Eko ni owon atunse ni nlanla ti won si nko ni ti Asiko, sugbon ko si eyokan ti won ko ni Mushin ni ti Asiko, sugbon ti w o n ba ri eniti o nkole ti won yio ri owo gba sapo ni won yio ma hale mo.

Laisi ayi pada ni aipe, emi Olofofo ko ni fi awon Oselu Mushin sile ni ose kan lati isisiyi lo titi won yio fi mu ise na se.

Nitori a ko mo ninu awon Omo Ile eko wonyi ti yio di enia pataki lehin ola, Nitorina ni awon agba papa se npa lowe pe " Igi ganganran ma gun mi loju okere lati nlo gun re. Eniti o jin si k o t o ko awon to ku logbon Isele ti St. Peter's School ti o sele ni o d u n 1955 eyiti omo mejo lo si orun are mabo. Kilo fa se bi Ile ti o ti di ogbologbo bi ti awon ile ti o mbe ni Mushin nisisiyi ni nitorina e fi eyi kun ero nyin kiakia.

Ni ose to'mbo ngo ma ba enyin omode s o r o nipa Aiye ti e fe ma sare ije. Toju Kobo meji re ni ose ti o mbo lati ra Iwe Irohin Imole.

IJAFARA LEWU

**Ma tan Ara re je mo**

Bi o ba daju wipe "IKO" tabi Amodi "IGBAAIYA" lo nyo o lenu ti ojo re si ti pe pupo, ma tan ara re je mo nipa rira awon "EGBOGI ROBIROBI" ti nwon nta kakiri Ode nisinsinyi ni owo poku. Won ko le se iwosan "IKO" ti ojo re ti pe rara. Sobu kan na ti o le ri orisirisi egbogi "IKO" ti o daju, Atamatase Ajebidan lati ilu awon Jamani, Faranse ati Itali (Tatabulu) ra ni Igboro Ilu Eko tabi ni sobu awon ara ilu Saro ti nwon npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)**

**IROHIN IMOLE**

**Takes A**

**New Look**

**this Week**

**2d in stead of 1d before**

Meet the Most exciting Writer

**Always read this new issue.**

## ORO PATAKI FUN AWON OBINRIN

Lati Owo:- Iyafin Alake

### O ha to ki okunrin fe Iyawo re pada, lehin ti o ti ko sile

IBERE; SI IYAFIN ALAKE:- Olotu jowo gba mi laye lati bere lodo Iyafin Alake pe, nigbati Okunrin ba ko Obinrin kan sile nitoripe ko tete bimo, o si ka si wipe, obinrin na nse agbere lo je ki oro re fi ri be, sugbon nigbati obinrin lo fe elomiran, o si bimo fun. Nje o ha ye ki Okunrin na tun fe obinrin na pada bi?

IDAHUN:- Gege bi aso lati inu Iwe Mimo, bi o ba je wipe oko lo ko obinrin re s i l e nitoripe ko tete loyun, lehin na ti o tun wa ri obinrin na, yala o bimo tabi ko bimo, o si fe lati tun fi se I y a w o re; Bi obinrin na ba gba lati se be, Oko na yio ni lati tun soyigi miran fun u.

IBERE:- Kini idi re ti Okunrin to ni Iyawo kan tabi meji, ti ko iti bo won yo daradara, ti o tun nlemu to awon obinrin miran lehin?

Emi ni

TAJU ADEBOHUN. AGEGE.

IDAHUN:- Agbere ni a npe iru Okunrin ti o ba nhu iru iwa be.

IBERE Iyafin, mo je obinrin Adelobo, mo ntaja, mo ni Oko kan nigbati mo fe, ko si ise lowo re to fi je wipe emi ni mo nbo; mo si bimo meta fun, nigbati o ya Olorun gbo adura ni o ri ise se, owo si wa lowo re, o wa fe Iyawo keji, o si wa feran Iyawo titun na ju emi Iyale lo, o nfun ni nkan ti o ba bere lowo re, sugbon ti emi ba bere owo lowo re ki fun mi, dipo ti ko ba fi fun mi nise ni yio damu mi: Mo fe amoran lati odo re, bi o ba je pe ki nkuro ni tabi ki njoko.

Emi ni

WULEMOTU AYOKA. EBUTE-METTA

IDAHUN Mo ba kedun f u n ibere re yio so mi lanu pupo pe o se o r e o wa di ibi, a m o r a n mi ni pe ki o joko ki o ma se lo, ki o ma se itoju awon omo ti o bi fun, boya Iwo ni o ko lori ki Oko se fun o. Ti o ba ti le ni o ko lo si ibo miran, ti arisiki ti eniti o ko lo ba ko ba ba o mu nko? Nitorina mo fun o ni amoran wipe, ki o joko ki o si ma ta oja re.

---

## Okunrin kan fi Ehin gbe Irin nla Soke.



Okunrin ti a nwo ninu aworan yi, ti oruko re je Terry Downer je okan ninu awon omo Egbe Abesekunbi-ojo nilu Oyinbo, osi je omo Gesi on ni anwo nigbati o dan agbara re wo ebere ofi Ehin mu okun ti won fi di Irin papo, osi fi gbe soke.

---

## Arowooye s'oku Baba re

ISOLO Ogbeni Lamina Arowooye Lawal se oku Baba re ni ojo Aiku ti ise egbon ojo osu ti o koja yi ni No. 8, ikoge Street Isolo. Irohin ko to afojuba ni inawo isinku na, malu mokanla ni o pa, o si fi jije ati mimu te awon alabaseye ojo na lorun.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon Alabaseye ojo na ni:- Oba I s o l o, Oba Oguwoye, Ogbeni Abu Gbajumo, Dada Akowonjo, Lawani Omopupa ati Okegbenro.

Baba oninure na ku nigbati o di eni odun mejidilogorun, o si fi opolopo omo ati o m o - o m o si aiye lo Orun rere o.

---

## Akiyesi fun Awon Onibara

A fi eyiyi se ikede fun gbogbo enyin Onkawe Irohin Imole kakiri Agbaiye pe enikeni ti o ba fe ra iwe Irohin Imole ni agbegbe ilu Kano tabi ti o ba fe polowo oja re sinu iwe Irohin Imole ki o lo si odo Asoju wa ti o wa ni gboro Kano ti oruko re nje FATAYI BISIRIYU ti ngbe NO. 46, FRANCE ROAD. KANO.

---


## Turari Ajebina Afarewole

Iye owo 10/6d pangolo, 5/6 idaji, le ekan si inu wa dun lati polowo Turari Aje bi dan Afarewole yi sinu Iwe Irohin Imole. Opolopo awon onibara wa ti o wa ni Oke-Okun ati Naijiria ti orugbe re ti ngbe, ni o ti nkowe si wa yala o wa nile Tabi ko si. Nisisiyi a ti see fun tita. o lagbara ni ilopo meta ju eyiti a ti nta ri lo.

IṢE TI TURARI YI NṢE

1.. O nle awon alujannu buburu jinna.
2 O njeki awon eni-ibi aiye yonu si enio.
3. O njeki adura tete gba.
4. Ki ijeki afefe buburu kolu enia.

Ti o ba nlo Turari yi, o ko ni mo nta oja, agbana ko si ni wonu igba re tete'ra tire loni nitoripe adura ni nwon : dura bi akara gbigbona

Wa ra tire ni Odo Manager:-

6,OJO ROD ODUABORE MUSHIN.

---

E ma mu Lucky Orange Crush nigba gbo gbo Oti to dara pupo ni

## Awon Olopa n w a Okunrin kan ti o se afowora moto

EKO:— A gbọ irohin wipe awọn Ọtẹlẹmuyẹ nwa ọ m ọ kunrin kan ti o ngbe Opopo ọna Idunmagbo nilu Eko, ẹniti wọn fi sun ẹsun wipe, o fi agbara ati tulasi gba moto ẹlẹdẹgbẹta Pọnun ni di Ọkunrin kan ti o jẹ ni ọ g ọ r u n Pọnun, o si lọ ta moto na fun ọkunrin ara Ijebu-Ode kan.

Ẹniti a gbọ wipe o ni moto na ni Ọgbẹni George Ajala ni Abule Alaluboṣa, ni agbegbe Ilu Ọyọ, a gbọ wipe nṣe ni ọkunrin na lọ g ẹ g u n soju ọna, nigbati moto na si nkọja lo, ọkunrin na ni ki drẹba ọkọ na sa bọ silẹ ki o si ma lọ.

Nkan yi ṣẹlẹ ni ọjọ kejidilogun oṣu July 1961. Ti ọkunrin na si tẹ ori bọ igbo, o si di awati

## Iye awon enia ti a fun ni ebun Eko O l o f e fun Odun 1961 si 1962

Enia mẹrindilogoji ninu awọn enia Dudu ti o mbe ni apa Iwọ Orun ilẹ Afrika ni Ijọba Gẹsi fun ni aye lati kọ ilọsiwaju Ọlọfẹ ninu Ẹkọ Olukọ fun ọdun 1962. Enia mẹtadilogbọn lo nlọ ni nilẹ Naijiria, enia mẹrin lati ilẹ Aganyin (Ghana) ati enia marun lati ilẹ Gambe.

Iwọn ẹdọtalelọdunrun ọmọ Akẹkọ ni yio gunlẹ si ilu Oyinbo Gẹsi ni oṣu ti o mbọ, nigbati nwọn ba de apapọ gbogbo wọn yio jẹ ọgbọnlenirinwo ti yio kọ ẹkọ nipa ilọsiwaju Ilẹ wọn fun ọdun 1962. Ninu awọn ti o lọ kọ ẹkọ ni esi, enia mọkanleladọrin, ninu wọn yio tun duro lati tun kọ Ẹkọ si fun ọdun keji.

Nwọn ṣe ipinnu ninu ile Ẹkọ Oxford University ti ọdun 1959 wipe Ijọba Gẹsi yio ma pese irinwo aye silẹ fun awọn ọmọ Akẹkọ lati ko ẹni kọkan titi fun ọ d u n marun ki o to ma pada bọ wa sile. Ẹkọ ti a ba kọ fun ọdun marun, Akẹkọ na yio ni ibiti yio ba de.

Enia mẹwa ti o mba wọn lọ lati Ilu E k o ni wọnyi. Ọgbẹni O. Ọwọyẹle lati Agege, M. A. Abidokun, Omidan E. A. Anga, Ọgbẹni A. O. Awotaiye, S. A. B. Odutayọ, B. O. Ọpara, C. A. Mọtọṣọ, G. E. Okunọlapọ, V. N. C. Nnwandu, M. O. Ogundipe, O. Okuboyejọ.

## Oloye Dennis Osadebay lo kara kun, asiki Igbeyawo Aburo Olola Benson



Ninu aworan ti a nwo yi ni a ti le ri Oloye Dennis Osadebay nigbati o nki Iyawo Ọlẹlẹ ti aburo Ọlọla Benson ngbe ni Iyawo Arede. Ẹniti o duro ni ọwọ osi aworan yi ni Ọlọla T. O. S. Benson. Ẹniti o duro tẹle ni O l o y e Dennis Osadebay ti o nki Iyawo ọlẹlẹ na. Benson kekere ti iṣe ọkọ Iyawo na loduro lẹgbẹ Oloye Osadebay na, Iyawo na paapa lo duro lẹgbẹ ọtun. Ẹ wo Iyawo na bi o ti nrẹrin muṣẹ.

### AKOWE LOYA K A N LUGBADI IJOBA.

IBADAN:- Ọdemọkunrin kan ti nwọn npe ni Samuel ti o jẹ akọwe alaṣiri fun lọya kan nilu Ibadan ni a gbọ wipe awọn Ọlọpa muwa siwaju adajọ fun ẹsun ole wipe, oji pọun marun le lọgọta lọdọ Okunrin Gbajumọ onisowo kan. Adajọ bere wipe, o jẹbi tabi ko jẹbi, Akọwe na dahun pe, rara on ko jẹbi.

Awọn Ọlọpa sọ wipe, ọkunrin Oniṣowo na ṣe iwe ti wọn fi ngba owo ni Bank aladọtalerugba Pọnun fun Lọya kan ninu ọdun yi, owo na jẹ owo Ile ti o ra lọwọ rẹ Nwọn mu iwe owo na fun Akọwe pe, ki o lọ gba owo na wa.

A gbọ wipe akọwe na da iwe pada lọ si ọdọ Oniṣowo na pe wọn ko gba iwe owo na ni B a n k Alalikua, o ti gba owo na.

### IJOBA GUINEA LE B I S H O B U AGUDA KAN JADE KURO NILU.

GUINEA: A gbọ irohin lati ilu yi pe Baba ẹgbẹ Sekou Toure, a ṣ i w a j u awọn Oṣelu ni ilẹ Guinea paṣẹ wipe ki Olori Alufa kan (Archibishop) ti Ilu Konakri (Conakry) ti o nṣe atako si ọrọ tabi aṣẹ ti baba ẹgbẹ ba pa wipe, afara ki o jade kuro nilu ki o si lọ fi di tisi ilu Dakar.

Nigbati Alufa na fi njade kuro nilu oga Ọlọpa ni wọn fi tẹlẹ wipe ki o mu de Ilu Dakar ki o to fi silẹ. Ohun ti a gbọ wipe o fa sa babi ti wọn fi wa Alufa na jade kuro nilu ni wipe Alufa Ijọ Aguda kan kọwe si Baba ẹgbẹ Sekou Toure wipe, awọn ko le gba ki Ilewe Aguda di ti Ijọba.

## Enyin Omo Yoruba, E ku Orire

Lati ọwọ:- M. OLANIYI
Z. I. GRAMMAR SCHOOL YABA

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye ninu iwe rẹ Oloyin mọmọ lati le ba awọn ọmọ Iya mi karọ ojire sọrọ itaji. Ẹnyin ẹlẹgbẹ mi, inu mi dun lọpọlọpọ lati ba yin sọrọ diẹ nipa Ẹgbẹ ti a ṣeṣẹ da silẹ ni abẹ iwe Irohin Imọlẹ ti orukọ rẹ njẹ EGBE IMỌLẸ AIYE. Nigbagbogbo ni mo ma ngbo lẹnu awọn ọmọ ile iwe ti wọn jẹ ẹlẹgbẹmi wipe Yoruba kodara to ede Oyinbo ati wipe ede Yoruba ko ṣe fi ṣiṣẹ, o dun mi wipe wọn ko ro ori wọn jinlẹ ki wọn to ma sọ jade. Ni ọna kini gbogbo ẹnyin ọdọ ni ẹ mọ wipe olukuluku enia ni o ni ede ati ẹya tirẹ gẹgẹ bi Ibo ati Hausa. Tẹlẹtẹlẹ ri Awọn Hausa nfi ede wọn, Ṣe idajọ ni Kọtu, eyi ko si di wọn lọna ati se ede Gẹẹsi. Nigbamiran ti o ba ri awọn ọmọ ile iwe meji ti nwọn ba nsọrọ, ni ede Yoruba o daju wipe yio sọ ede Gẹẹsi bi meji tabi jubẹ ẹ lọ ninu ọrọ marun. Nitorina ohun ti o le mu ki, a ma sọ ireti tabi Ire wa nu, on ni wipe ki a di ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ti o jẹ akọkọ ati eyi ti o le gbe orilẹ ede wa ga julọ, gẹgẹ bi emi na ti ṣe jẹ ọkan ninu ẹgbẹ na.

## Olori Alakuko ko Omo Egbe re s'Olope

O l o r i gbogbogbo ẹgbẹ Alakuko, Ọgbẹni Okpara ko ọmọ ẹgbẹ rẹ pe ki nwọn maṣe bikita lati ba ẹnikẹni ja larin ilu nigbati ọmọ ẹgbẹ Olopẹ da wọn lamu, O ni bi Ọlọpa ba da lamu, ki awọn na yọ wọn lẹnu.

Olori ẹgbẹ nsọrọ nipa rogbodiyan ati rudurudu ti awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ so wipe o ti de si Ipinlẹ Iwọ Orun. Nigbati o wa ni Oke okun, awọn ẹmẹwa rẹ ninu ẹgbẹ fi waya pe ki o tete wa sile nitori rudurudu ti bẹ sile Ipinlẹ Iwọ Orun ati pe ko si si ofin mọ.

Ki nwọn to fi waya yi ranṣẹ si OKPARA, Olori ijọba apapọ Naijiria ni nwọn koko fi iwẹ ranṣẹ si. Ṣugbọn Alhaji Tafa sọ wipe itọ ni pe rudurudu ti bẹ sile ni ipinlẹ iwọ orun. Alhaji ni ti o ba ṣe bẹ ni ko si ẹniti yio sọ fun on ki on to mọ. Lẹhin idahun yi ni awọn ẹmẹwa olori ẹgbẹ alakuko tẹ waya si Okpara pe ki o tete ma bọ nitori ipinlẹ Iwọ orun ti fọ, ofin ko si si mọ.

Bi Olori ẹgbẹ wọn si ti de, o wọ moto lo si Enugu, o la Iwọ orun koja ki o ba le fi oju ara rẹ ri ohun ti o gbo. Ni ọjọ Satide 26:8:61 ni o kọ awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ si ẹgbẹ Olopẹ pe ti nwọn ba da nwọn lamu ki nwọn da nwọn lamu pada. Ni ilesha o sọ fun ọpọ enia pe ako ko ti to ti ọmọ ẹgbẹ on ni lati ma lo agbara ti wọn na lati ma ba ọmọ ẹgbẹ Olope ja.

O ni awọn Ọlopa papa ngboju kuro ninu iwa buruku ti ọmọ ẹgbẹ Olopẹ nhu. Nitori eyi o ni ki awọn ọmọ ẹgbẹ on maṣe nani Ọlọpa mọ. O ni ti Olopa ba da wọn lamu ki nwọn da lamu.

Ṣugbọn kete ti Okpara de Enugu ni o ri iwe ẹsun gba lati ọdọ awọn ọmọ Kalaba pe ijọba ipinlẹ Ila orun ntẹ awọn mọlẹ, nwọn si nfi iya jẹ awon. Ninu ẹsun yi nwọn fun Ọgbẹni Okpara ni ibere mẹsan ti o tọkasi iwa afiyajẹni ti ijọba ila orun nhu si awọn ẹgbẹ ti ko faramọ ẹgbẹ alakuko,

## PAYAL

Ojulowo E g b o g i kokoro tio lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba, Alefo. Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adaajinọ egbo, ekuṣẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisu, Akọ Inarun ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi titun ti awọn ara Ilu Tatanbulu ṣe ti wọn npe ni "PAYAL" wo larin ijọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu. E g b o g i ipara yi ki ṣe awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si şişe iye meji ninu lojẹ eleyi si yato patata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu. Orişi meji rẹ lowa. Kekere ati Nla.

Bere egbogi ajẹbina Payal yi ni ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## Oyinbo yi ni Olugbala Awon Geesi



Oyinbo yi. ti a nwo ninu aworan je asole (Goalie) fun awọn elere bọlu afesegba ti Gẹẹsi Ṣawo bi o ti fọ wa mu bọlu yi, O r u k o rẹ ni Willie Duff. O si ngba bọlu fun Charlton Athletic Football Club.

**Ma a ka Irohin Imole**

